# ENMO PELEMBE, OYINBO WOLE-WOLE JI EJA PANLA





SEE YOU PAY THE CORRECT PRICE.



ELETI OFE
A-NJU-WON KO SE WI L'EJO





AWOGBA Omode fun Girl, Eyi, Hiku-ekin, Orere. Ra Tire Ni Ile Egbogi — ISE — Olodus are Okebola, Ibadan. 116, Great Bridge St LAGOS



VOL. No. IX 517. ELETI - OFE LAGOS, SATURDAY, APRIL 27, 1957. KOBO MEJI (2)


## Enmo pelembe, Oyinbo wolewole ji eja Palapala

KAMERUN Ninu ṣobu awọn oyinbo U.A.C. ni oyinbo kan, ti a ipo rẹ ga jọjọ ninu iṣẹ ijọba ti lọ ji apo ẹja Palapala mẹrinla gbe ti ọwọ ọlọpa si tẹ ẹ. Oyinbo na sọ wipe, on gẹgẹbi olotu iṣẹ ilera ilu sọ wipe awọn apo mẹrinla na ko dara fun jijẹ. Njẹ ki onjẹ ma ba ṣofo danu, on gbero lati ta awọn apo mẹrinla na fun awọn Onișowo ẹja Panla ni ogun Poun.

Nigbati awọn Ọlọpa ranṣẹ pe oyinbo U.A.C. wipe bawo ni tt ẹja ti jẹ, O si dahun pe ọga agba ni ọdaran Oyinbo na jẹ nibi iṣẹ ilera ilu, o sọ pe awọn apo ẹja mẹrinla na ko dara mọ fun jijẹ. Gẹgẹbi o si ti jẹ aṣa pe ijọba ke gbọdọ gbo onișegun lẹnu, ambosibọsi awa abori kura, eyi lo jẹki nfi awọn ẹja na silẹ fun.

Nigbati ọdaran oyinbo na ma dahun, o wi fun adajọ pe, ki o fori ji on, on ni iyawo kan lọwọ on si ni awọn ọmọ mẹta ti on nran lọ silewe, ohun ti o jẹki on ṣe bẹ ni wipe, ibu ni ko to iro fun on.

Adajọ wo o titi, o mi ori, o ni ki o lọ san adọjọ Poun, bi bẹkọ ki o lọ si ẹwọn oșu mẹfa pẹlu iṣẹ aṣegan.


**THE NATIONAL BANK Of Nigeria Limited**

Incorporated in Nigeria in 1933
Paid up Capital – £1,130,000
Bankers to the Western Region Government of Nigeria.
HEAD OFFICE
37, MARINA, LAGOS, NIGERIA
22 Branches throughout Nigeria including IBADAN, ABEOKUTA, IJEBU-ODE, OSHOGBO, OWO, ONDO, ILESHA, ILARO, BENIN-CITY, WARRI, SAPELE, ABA, KANO, ZARIA, JOS.
LONDON OFFICE
1 THROGMORTON AVENUE, E.C. 2.
Manager: F. O. Tyrrell
Telephone: London Wall 4303
Cables & Telegrams: Natbaniger, London.
Head Office Representative in London
Ernest Olubunmi Obasa—Porter
CORRESPONDENTS
NEW YORK PARIS HAMBURG


## Ero lona ile Hausa



**Councillor Taju Thompson**

Aworan ti e nwo ninu iwe wa yi niti Alakoso ise Iwe Irohin wa Eleti-Ofe (Managing Director) yi, on ni o dakan lo be ile Oke-Oya wo, nilu awon omo Alahusa.

Alo a dara abo a sunwon o - Alakoso Tiwa'

## Baba kan ponmo Airotele

Ọkuurin arọ kan ti o si wipe gbogbo enia nsare fun ojo ori Kereni, ko si fẹ ki ojo ti o mbọ na pa on o pe ọkuurin kan ti o nsare koja lọ pe ko wa, Bi eleyi niti bẹrẹ lati gbọ ohun ti w, nṣe ni arọ na fọmọ lọrun o wipe ayafi bi o ba gbe on de Idumọta. Gbogbo enia bẹrẹ si ke wipe Bala Ponmọ airotẹle.




## Egbe Onisegun Fi Ejo Ijoba Sun

Eko - Awon egbe awujo Onisegun (The Assoc. of Federal Medical officers) ti Oyinbo fi ejo ijoba sun wipe, awon ohun elo ti o wa fun lilo ni ogba Alarun ko to rara, nitori idi eyi iwon igba (200) enia lo nsalaisi ninu ogba na l'osusu.

Ibe ni Ogbeni Aja Nwasuku, ti onse Minista fun ise na dahun pe rara, oro na ko je bi awon egbe onisegun ti so. Nitoto enia ko salaiku sugbon ko ju iwon enia mokandiladorin lo ninu osu kan lodun to koja. Ati wipe ile Alarun na ko se alaini awon ohun elo to, ati wipe awon orisirisi ogun ati awon egbogi titun to sese de, gbogbo re lo mbe ninu ipamo ninu ile eru.

Ijoba si ti se eto lati tunbọ ranṣẹ fun awọn ibusun lati fi kun eyiti o ti wa nibẹ ri. Nigbati ijọba ba pari gbogbo eto ile Alarun yi tan, on ni yio jẹ eyiti o dara julọ ni gbogbo ilẹ Nigeria. Pẹlupẹlu ijọba nfẹ da igbimọ kan silẹ fun awọn awujọ Onişegun nwọnyi.

Ninu iwe ti awọn awujọ Onişegun nwọnyi kọ si Ijọba, nwọn sọ pe, ayafi bi ijọba ba şe nkan ti nwọn fẹ fun wọn, bi bẹkọ, gbogbo awọn Onişegun ni yio binu da işẹ silẹ.

## Adajo To Dajo Sanwo Odaran

VICTORIA. A gbo wipe awon olopa mu moto obinrin kan ti ko gba Iwe-ase ti osi nrin lori oju Titi oba wa s'waju adajo.

Adajo da iya na lebi pe, ese ti ko fi lo gba licence re, nigbati iya na ko le so, ni adajo ba sa konko le wipe ki o lo san Poun kan.

Nigbati iya na gbo oruko re a ma je Madam Ogun, o kigbe rara wipe nibo ni on yio ti ri Poun kan san,

Lenu ojo ti ko pe yi ni ina jo ile ti on fi owo iyebiye ko, ofo edegbeta le ni egberun poun ni on se.

Anu re se adajo yi, o si yo owo jade ni apo ara re, o si sanwo na.

## Okunrin kan ku somi nigba odun Easter

EKO. Ọdọmọkunrin kan, ti o jẹ gbajumọ lo ko awọn obinrin Sodẹ ati awọn gbajumọ lọkunrin ati lobinrin sinu mọto, lati lọ lo faaji ati isimi ọdun Easter ni eti omi Kuramo. Nigbati o de ibẹ, o ba awọn orişirişi enia l'oyinbo ati l'enia dudu, nwọn pagbo ti wọn lọtọ, nwọn joko, nwọn jẹ, nwọn si mu, nwọn yo tan, nwọn wa fẹ iuwẹ ninu odo.

Ọgbẹni Solomon Olu. Babayẹmi ti o ngbe Ikoyi, ti o si jẹ ọkan ninu awọn oşişẹ Barclay's Bank lo kọkọ bọ si odo. A gbọ pe bi ọkunrin yi ti şe şọlu sinu odo, alọ ni nwọn ri, nwọn ko si ri abọ rẹ mọ.

Nigbati o şe niọ si bi iwọn işẹju mẹwa ti ọkunrin na ti şe sọlu sinu odo awọn ọrẹ rẹ fi igbe ta, ati oyinbo, ati enia dudu lo sare bọsi inu omi,, ti nwọn si bẹrẹ si wa ọkunrin na.

A gbọ pe nigbati nwọn fi ma ri ọkunrin na, o ti di oku, bẹni ọkunrin na ba ku bamu-bamu.

## Igbimo Ilu Oba Ti Akoko.



Awọn ti a nwo ninu aworan yi ni ipade eto ilu ti nwọn lọ şe nilu Oyinbo eyiti Ọgbẹni Lyttleton şe alaga le lori. Ọlọla Awolọwọ lo dide duro ti o nsọrọ ti o si wọ aşọ funfun, awọn aşoju ilẹ Hausa lo joko to kọ ẹhin si 'wa. Awọn aşoju lati Ila-Orun lo joko lapa osi, Olukuluku pẹlu akọsilẹ niwaju rẹ.


# M.B.T.

(MAGIC BLOOD TONIC)



Iná dé, òkùnkùn paradà. M.B.T dé, òkùnrùn fò lọ. Ẹ̀jẹ̀ dúdú sárá. òyì pòşèşè. Àlá buburú wọ'gbó. àìlèsùn r'ẹ̀hìn-ẹ̀kùn. M.B.T. l'ògùn-ẹ̀jẹ̀ ti nmú ni jẹun b'ìkan, amú ni yàgbẹ́ bi ọ̀kùn, amú ni tọ̀ bi àkèrè. Abiwẹ́rẹ́ f'ábọyún, agbẹ̀jẹ̀dá f'awọn abiyamọ. Ahọ́n-dúdú, ẹsẹ̀-wíwú ati àìyà-jíjá ko si pẹ́nití nlo o. 4/6d pẹ̀lú 1/6d owó-ọkọ̀.

ARADAN STORES P.O.Box 2 EBUTE-METTA.

**Your PAIN is here**
*This chart shows parts of the body that suffer when your kidneys are not working properly*



**DeWitt's**
**Kidney & Bladder Pills**
act directly on your Kidneys to clear out poisons that cause pain

**A few hours** after taking DeWitt's Pills you will have unmistakable evidence that this wonderful medicine is already at work—stopping
RHEUMATISM, JOINT PAINS
BACKACHE & BLADDER TROUBLES




**DeWitt's**
**Kidney & Bladder Pills**
*Praised by sufferers all over the world for over sixty years*

WE EXPORT ANYTHING
Brass Beds, Iron Beds, Printing Plant, Cameras, Generating Sets Pianos, Organs, Typewriters. All Musical Instruments.
Aldershot Warehouses Ltd., Aldershot, England.

**Polowo Oja Re**
**Sinu Iwe Eleti-Ofe**
**Ki E Si Ma Ka**
**Fun Irohin Aladun**

**IMORAN FUN ENYIN ABIYAMO**

Enyin abiyamo e wa ra OMORELA o dara pupo fun awon omode.

Ama je ki omode ri oran sun daradara o dara fun otutu, ike ati orisirisi arun miran ti o ma mba omode ja ni asiko ehin. Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun omo won ti won si so wipe odara pupo fun awon omode

OMORELA BABY MIXTURE
*(SILE MEJI ABO 2/6d. FUN IGO KAN)*

O wa lodo :—
COMMERCIL MEDICINE STORES
(Qualified Chemist)
10, VICTORIA STREET, LAGOS

# Ofin titun bere ni Ifo

IBADAN. Ijoba Iwo Orun ti fun awon igbimo ilu Ifo lagbara lati ma se awon nkan nwonyi, eniti o ba ko lati se awon nkan na yio se si ofin ijoba. Awon ilo ofin titun nwonyi yio bere lati ojo kini osu April 1957.

1. Enikeni ti o ba ngbe ilu Ifo, tabi agbegbe re, ti o ba ni keke Basikulu, Moto, Omolanke tabi Moto Cycle tabi ohunkohun ti o le gbe enia rin yio gba nomba si ni ilu Ifo.
2. Enikeni ti o ba bi mo, ko gbodo ma gbawe ojo ibi re lodo awon Wole-wole, bakanna ni bi enikeni ba ku, yala omode tabi agba ko gbodo ma gbawe oku re.
3. Enikeni ti o ba fe se nkan ayo, tabi iyawo tabi oku tabi jo ijo agbe ti o sio fe lulu nibe ni lati gbawe ki awon to bere si lu.

# Enia Nfo Bi Eiye

Laipe ti a wa yi, oju enia yi ori amimo. A so fun wa nihu ilan wipe okunrin ojogbon kan ti o npe ni Socrate ile koko kan nwon ako iye mo apa osi fo bi eiye lati ilu Athens si ilu Griki. A gbo pe eyi ni awon ojogbon ronu le lori ti awon fi se oko Ofurufu, lyen be.

Irohin ti a tun gbo ni wipe, okunrin ojogbon kan ara ile Kalifonia lo se ero kekere kan gegebi ti oko ofurufu, o ka a mo ehin re lo ba ta pa gegebi ti moto, aya fi ra re, re ti ero yi ngbe lo, ero na ngbe fo ni dede ilu Eko si Olekemeji ni wakati kan. Emmo Pelembe, arugbo ntage, ohun ti oju ma ri si ku.

Ero na fo ga soke orun ni ogorun ese, gbigbe ti ero na gbe okunrin ti o dabi igbati agbe alangba.

# Eyiyi Su Mi Jojo

Omo ile e ti o nka A. B. D. kan lo mbinu bo wa sile lati ilewe. Bi e ti de, o wipe Ho-o-o, Iya mi o, ako ni lo si lewe yi mo.

Iya re si bere wipe, ye! omo mi, ki ni ohun ti o de bayi?

O si dahun pe, ma da tisa yen lohun o jare, ni ojo Atalata, o so wipe ela ati eji je mejo. Ni ojo Alaruba o tun wipe erin ati erin je mejo ati lojo Alamisi, tisa yi kanna tun so wipe, eje ati okan tun je mejo.

Aha! isokuso ni eyi, bawo lo ti se ni lati je be iro ni, ko ni lati je be rara.

Iya re ku serin, o wipe omidara, omo mi, bi o ba di ojo Monday ngo yo kumo lo ka tisa na mole ngo si ba je gidigidi.

**Kere o!**

A ti ni orisirisi ogun Germon to sese de, fun onigura aisan tokunrin tobinrin. Tete wa ra tire k'o to tan.

I. A. AJAO
BROTHERS
MEDICINE STORES
7, Egerton Road, Lagos.

# ELETI ỌFẸ

A-NJU-WỌN KO SE WI L'EJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS 28, Kosoko Street, Lagos P. O. Box 467

CABLES & TELEGRAM "ELETI - ỌFẸ LAGOS" Phone 23370

VOL. IX. NO. 517, LAGOS, SATURDAY APRIL 27, 1957


## E Wa Wo, Ohun Ti A Bajo Wo L'o Ngun

Kosi ẹniti ipade ajọro ti Ọlọla Ahmadu, Sardauna Ṣokoto pe ti awọn Ogunna gbomgbo wa mẹtẹta jijọṣe nile Gomina agba nilu Eko fun ajọṣọ ọrọ ni ifohunṣọkan l'ori ọrọ eto ilu Nigeria wa yi ko dun mọ ni ipinlẹ mẹtẹta to mbẹ nilẹ Nigeria ti ilu Eko jẹ ẹkẹrin rẹ.

Aṣọ eyi laifọtape wipe o dun mọ ẹru, o dunmọ ọmọ, o dunmọ onile beni o si dun mọ alejo kakiri ilẹ wa gẹgẹbi irohin ti a gbọ ati eyiti a nrika ninu awọn iwe irohin le ipade alarinrin na lori. Nipa bẹ, a ni ifọkanbalẹ wipe ipade nia ti awọn akonijẹ wa yio ṣe nilu Oyinbo laipẹ yi yio yọri si rere l'agbara Allah.

A fi wosika wa yi ki ọlọla Ahmadu, Sardauna Ṣokoto ti o ṣe okunfa ipade na, bi a ba ki oniyan, o yẹ ki aki ọlọka, ki a si wa ki ẹniti o jẹun papa ku arọju jẹ; nitorina, a ki ọlọla eloye wa Ọbafẹmi Awolọwọ pẹlu Dokita Azikiwe ku ifẹ ilu wa ti awọn ẹni-nla mejeji na fi tọwọ-tẹsẹ jẹ ipe ipade ọlọla Sardauna ti ọrọ wọn fi bọsi bakanna, ti awọn si ṣe ni "inu kanna ni ọmẹ oniye njẹun si" bi owe Yoruba.

Eyi wu wa o

## Abami Ore meta

Awon enia meta kan ti wa ri, ti nwon je ore arawon, oruko ekini ama je Aramasan ekeji a si ma je Atamatawin eketa a ma je Aworan-baranku.

Ni ojo kan ebi npa aramasan beni onje ni Atamatawin nta, nigbati o se ni Aramasan lo ba Atamatawin ore re, o si ra onje, o jeun o yo daradara, o fe ma lo, ni Atamatawin ba bere owo lowo re, o si dahun wipe ni ojo ti iya on ti bi on s'aiye, on ko ra oja ki on san owo ri.

Atamatawin ni hen! lati ojo ti baba on ti fi oja le on lowo, on kota awin ri, ni ija ba be sile, Aworan-baranku ni on a ridi gbogbo re, nibiti nwon ti nja ni Atamatawin gbe Aramasan sanle, ni iku ba de. Atamatawin ni bi o ba je ti iku ni, on yio ba e d'orun lo gba owo na, beni on na siku sibe.

Aworan-baranku ni on yio ba won d'orun, ki on le ridi gbogbo re, beni on na sun ti won, o si ku. Enyin okawe wa, e jowo tani jebi ninu awon ore metata yi?

## Oba Oni Ile Ife



Ẹniti a awo yi ni aworan Alaiyeluwa ọba Ọni Ile Ifẹ, ẹniti o ti ba ọkọ oju omi lọ silu Oyinbo fun ọrọ ajọṣọ kan ti yio ṣẹlẹ nilu awọn oyinbo nipa igbega ati ilọsiwaju ati omialara ilẹ wa Nigeria. Ọba Ọni lọ silu Oyinbo na gẹgẹbi aṣoju fun Igbimọ awọn ọba ilẹ Yoruba ati gbogbo awọn ọba ni agbegbe Iwọ-Orun Nigeria.






E Ma Ka Iwe Irohin Eleti-Ofe Fun rohin Aladun Ki E Si Ma Polowo Oja Yin Sinu Re

# Awon to fe j'oba F'oruko pamo

Irohin kan wa wipe awọn to fẹ lati jẹ ọba Oluwo ti ilu Iwo dipo Ọba Oluwo to w'aja ni oṣu tokọja ni a gbọ wipe ninu wọn ti o jẹ Kiriyo (Onigbagbọ) nfi orukọ isami wọn pamọ nitoripe isin Imale l'ogbilẹ ju nilu Iwo.

A gbọ pe enia marun lo ndu ọba na lati jẹ lati inu ile Lamuye nilu Iwo. Oloye S. I. Ogunwale ti iṣe Oloye Ẹkẹrin nilu Iwo ti o si tun jẹ ọkan ninu awọn afọbajẹ ni a gbọ wipe o ṣe alaye pe ẹniti yio ba jẹ ọba Oluwo, gẹgẹbi o ba ti ṣenia nilu si ni awọn afọbajẹ yio wo, nwọn ko ni ka ti mo m'ọwe si, ọmọwe ni mi, ko ni jẹ pataki to le mu enia jẹ ọba ayafi bi oluwarẹ ba jẹ ọmọluwabi larin ilu Iwo.

Awọn ti a gbọ wipe awọn ndu oye ọba na ni Ogbẹn S. O. Abimbọla, Tafa Moluberin, N. O. Abanikanda, I. Jankuri ati A. Adedokun. Awọn afọbajẹ mẹtadinlogun ṣe ipade aṣiri lọsẹ tokọja.

ooooooooooooooooooooo

# First African Appointed Asst. G.M. (Staff)

The Nigerian Railway Corporation announces the appointment of Mr. Nelson Adeyẹmi Kuforiji as Assistant General Manager (Staff) with retrospective effect from 24th October, 1956. Mr. Kuforiji who was appointed Deputy Assistant General Manager (Staff) last year had been acting in this new post since that date.

He joined the Nigerian Railway in 1926 as a Trafic Learner. He became third class Station Staff in the same year, second class clerk in 1928, first class clerk in 1940 and Assistant Chief Clerk in 1942. He entered the 'Senior Service in 1948 as Assistant Establishment Officer and was promoted Establishment Officer in 1951 and Senior Labour Relations Officer in 1953.

When the Corporation established an office in London at the beginning of last year, Mr. Kuforiji was sent as Assistant Representative.

# Ijoba Tilekun Ile Owo Ilu Ẹpe

A gbọ irohin lati ọdọ ijọba wipe, ile iṣura ti ijọba kọ silu Ẹpẹ, yio duro, o si ti duro lati ibẹrẹ oṣu April 1957.

Aibamọ, gbogbo ẹnikẹni ti o ba ni nkan ṣe pẹlu ile iṣura ilu Ẹpẹ, ki o mu lọ sile iṣura kekere kan ti o wa ni ilu Ijẹbu Ode.

Ile iṣura owo (Treasury) ti kuro nilu Ẹpẹ, ni Ijẹbu Ode lo gbe wa nisisiyi.


*Family links with*

**THE UNITED AFRICA COMPANY LIMITED**

*Recording some of the many families who have found interesting, varied and worthwhile careers with the U.A.C.*

Many years ago Chief Okorodudu, son of the Olu of Warri, took his family on a trading expedition to Burutu. There he founded the village that still bears the family name, the village of Okorodudu. In 1952, in honour of the Chief, a vessel of the Niger River (Transport) Fleet was named "Okorodudu", and his portrait can be seen on the ship's bridge. The ceremony was performed by the present head of the family, Chief Eruwa Okorodudu.






*Members of this family have served with The United Africa Company and its predecessors continuously since 1900. Their total length of service exceeds 160 years. The Company is proud of this unbroken link with so distinguished a family.*

Chief Eruwa Okorodudu



**The Okorodudu Family**

The Record of Service of past and present members of the Okorodudu Family

J. E. Okorodudu 47 years' service*
E. A. Okorodudu 38 years' service
S. N. Okorodudu 24 years' service
S. O. Okorodudu ?? years' service
E. Okorodudu 10 years' service
G. Okorodudu 9 years' service
G. O. Nesiama 7 years' service
O. O. Okorodudu 5 years' service
A. O. M. Okorodudu 4 years' service




Our pictures show some of the Okorodudu family working for the Company

# Eiye Awo Ati Malu Nse Ore

Nigbakan a sọ fun wa wipe, ẹiyẹ Awo ati Malu mba ara wọn ṣe ọrẹ, nwọn si njijọ da aṣọ lọ sode. Ọrẹ wọn na pọ tobẹ ti awọn ẹiyẹ ati awọn ọmọ ẹranko yoku fi njowu wọn.

Ohun ti o wa da ọta si arin meji wọn ti nwọn ko tun fi mba ara wọn rin pọ mọ ni wipe, ẹiyẹ Awo jẹ ẹniti o nmu aṣaa (T ba) bẹni Malu na nmu. Iya aṣaa wa mu tobẹ ti o fi jẹ wipe gbogbo awọn ẹiyẹ, enia ati ẹranko ti o nmu aṣaa ni ko ri mu mọ.

Malu wa pe ẹiyẹ Awo wipe, ki o jẹki nwọn jijọ wa aṣaa lọ. Nwọn dide nwọn wa a lọ, nwọn si ri si ilu kẹdogun. Awo ra ẹlẹgbẹrun, Malu ra ẹlẹgbaa ki wọn to pada dele Malu ti mu aṣaa tirẹ tan.

Nigbati awọn dele tan, Malu tun nfẹ mu aṣaa bẹni o ti mu tirẹ tan loju ọna ki o to dele, o wa koju si Awo, o wipe "Bun-mu-u Ẹiyẹ Awo si dahun wipe "Ṣo bẹ" Itumọ rẹ ni pe, nigba ti Malu sọ wipe "Bun mi mu tabi fun mi mu" Awo si dahun pe "ṣe o bẹ tabi ṣe iwọ na ra" Eyi ni ọrẹ wọn fi tuka ki Malu to wa yan Lekeleke ni ayo.

# Ofin titun bere ni Agege

IBADAN – Ijọba Iwọ-Orun ti fi ase fun awọn igbimọ ilu Agege wipe, gbogbo ofin ti awọn ba ṣe lori ọja Agege ni awọn ni lati mu ṣe. Ẹnikẹni ti o ba kọ lati mu awọn ofin na ṣẹ oluwa rẹ yio lufin

2. Ẹnikẹni ti o ba ni kẹkẹ Basikulu, Mọto, Ọmọlanke, Motor Cycle; ti lati bẹrẹ si gba iwe aṣẹ fun wọn lati ọjọ kẹrin oṣu April 1957 lọdọ awọn igbimọ na.

# Ẹdẹ Larubawa ni Jesu nso

Lati ọwọ
LEMỌMU AJAKUTA

Abraham to jẹ baba ati Olupilẹṣẹ Igbagbọ ede Larubawa lo nsọ. Nigbati o bi Ismaila tabi eyiti awọn Kiriyo npe ni Iṣimẹl ede Larubawa lo nsọ titi nwọn fi pinya pẹlu ọmọ na. Ati nigbati o si bi Isiaka eyiti awọn Kiriyo npe ni Isaac ede yi kanna lo nsọ

Ibi ti Haga tabi Hagai gbe bi Ismaila si lo di ilu Mẹka loni, ire ti Abraham su fun ọmọ rẹ lọjọ ti o lo bẹ wọn wo lo nṣẹ lori Mẹka titi d'oni.

Lati idile Ismaila ni Larubawa ti ṣẹ, ati lati idile Isiaka ni ede Heburu ti ṣẹ. Gbogbo awọn Ọkẹ mẹfa le lẹgbaji awọn Anọbi ti Ọlọrun ran niṣẹ, Ọlọrun gbe wọn dide lati inu idile Isiaka. Anọbi Mọhammad ni Ọlọrun gbe dide ninu idile Ismaila,

Tani kọ mọ pe Larubawa ni Jesu sọ nigbati o sọ wipe Eloi, Eloi, lamasabaktani. Larubawa rẹ niyi 'Allaha, Allaha lama Sabakta ni. Itumọ rẹ ni Ọlọrun, Ọlọrun Iwọ ha ti fi mi silẹ ni bi

Ati nigbati Jesu sọ pe Talitakumi Larubawa rẹ ni Ta-al, anta Umi, ọbinrin yi, dide wa

# Ijoba lowo si jije oye nwonyi

Ijọba Iwọ-Orun ti fi aṣẹ ti otitọ ijọba tẹ orukọ awọn enia nwọnyi gẹgẹbi Oloye.

1. Adeyanju Ogunjọbi ọba ilu Ipokia.
2. Jọṣua Ogunbiyi ọba Oloke-odan
3. Benjamin Adesọla Gbelẹyi ọba ilu Igbẹsa
4. Raji Oyebisi ọtun Balogun Oshogbo.

# Olojo Ibi, Ojo Ayo



Ni ojo Tuesday ose yi ti ise ojo ketalelogun osu April 1957 ni a se ayajo ojo ibi Alaiyeluwa oba Obinrin Ilu Oyinbo Gesi, Elizerbeth keji, nilu Eko, ayeye ojo na mirinigindin.

Awon egbe omo-ogun (Soldiers) fi ijo da bira ni gbamgba teju, ti a npe ni odan (Race Course), ki o wa wo bi ese ati apa omo enia ti njo welewele pelu ihamora to gbamuse,

Lotitọ, ọjọ ayọ ni ọjọ ibi

No. 57.

## Geological Survey Department

VACANCY FOR LIBRARIAN.

Applications are invited for the post of Librarian, Geological Survey Department

Particulars in Government Notice No 668 in the Federation of Nigeria Gazette of the 11th of April, 1957.

E Ma Ka Iwe Irohin
Eleti-Ofe Fun rohin Aladun
Ki E Si Ma Polowo Oja
Yin Sinu Re

## Eri okan mu ole

Okunrin Olopa inu kan ti wa nilu Eko ri ti nwon npe ni Ojo Wonkoko, ko nmu enia ki oluwa re bo kuro lowo ewon.

Irohin de odo re pe awon olosa da oyinbo kan lona ni Ori Oke Efon, nwon si ko gbogbo eru re lo. Nilu kan ti nwon npe ni Imesi Oloja Oke ni Ojo ti fura si eni kan, okunrin na ko lati jewo, sugbon Ojo wipe, bi o jewo tabi ko jewo, ko sa niso ni Eko beni okunrin na ko de ilu Eko ri.

Nwon fi Pawope (Handcuffs) si okunrin na lowo, Ojo si ti siwaju o wifun pe, se iwo ko lati tete jewo ibon ni nwon o fi pa o. Iwo koiti mo ilu ti o de yi. Nigbati nwon mbo lori kereni, beni moto alaru kan yin bon idi gbola! Ojo so wipe, ota ko ba, e lo kabo.

Okunrin na rope on ni nwon nfe pa, lati gba na ni okan re ti fe jewo. Nigbati nwon de ehin Ogba moto miran tun yin bon idi gbola! Ojo tun so pe koiti ba a, nse ni ki e yin bon pa, Okunrin na gbon jini-jini, o wipe Awe! o ku yeye, dakun dabo ma pa mi, ma ya jewo fun e.

Ojo si dahun pe bi o ba tile jewo ti o tu asiri ore na, ehun kan ko ni se o iwo yio si pada si Ilesha lalafia.

Nigbati nwon de Kotu Santana, on lo se ona ti nwon fi ri awon yoku mu on na leniti o tako awon yioku ti nwon fi ri gbogbo eru oyinbo na gba pada.

Ojo Wonkoko lo se e.

## Ona Ti Eru Gba De Ilu Aguda

Nigba lailai, awon Hausa nta eru fun awon Tapa, awon Tapa nta a fun Yoruba Yoruba nta a fun Ijebu, Ijebu nta a fun Eko Eko nta a fun Potogi (Portugees) ati Payan (Spaniard) nwon o si fi gba ota, aso, oti ati ibon.

## Awon enia ti o nlo soju fun Hausa niyi

Kaduna - Ninu ipade ti nwon nlo se nilu oyinbo, awon enia nwonyi ni awon Hausa yan lati lo se asoju fun awon egbe Oselu kokan. Awon oba meta lo nlo se asoju fun Igbimo awon oba ati Ijoye ile Hausa Oruko won njyi Alhadji Sanusi, oba Kano, Alhadji Usman Nagogo oba ilu Katsina, ati Malam Ali Abaje oba Igala.

Awon Egbe N.E.P.U. Mallam Aminu Kano ati Mallam Ibrahim Imam, awon enia ti yio je alabaso won lohun ni Alhadji Sule Maito.


# SPECIAL OFFER

Largest in the East

# 375,000/- to be won

IN EAST ASIATIC COMPETITION

355,000/- for all correct; 20,000/- for first two rows correct, (only if jointly correct).

| | | | |
|---|---|---|---|
| | | | |
| | | | |
| | | | |
| | | | |

Arrange number from 22 (twenty two) to 37 (thirty seven) in the squares so that the total should be 118 (one hundred and eighteen) when added vertically, horizontally & diagonally or from all sides. Each number should be used once only. Last Closing date: 23/5/57 (by air). Result: 31/5/57.

Entrance fee: 20/- for one solution, 40/- for four solutions, 80/- for sixteen solutions, 100/- for 24 solutions, 120/- for 32 solutions and so on.

RULES:- Any number of Entries on plain paper along-with prescribed Fees at the above rates may be sent.

| Last Result Total 114 | | | |
|---|---|---|---|
| 29 | 26 | 27 | 32 |
| 24 | 35 | 34 | 21 |
| 36 | 23 | 22 | 33 |
| 25 | 30 | 31 | 28 |

Fees may be sent by British Postal Orders or money order. Use English figures for the solutions. The solution or the rows Shall be treated as correct only if they are similar to our official sealed solution.

Correspond in English only. Send 1/- extra for result. (For air reply send 2/- extra)

The Promoter's decision Shall be final and legally binding and is an express condition for entering this Competition.

Address your Entries with fees to:

EAST ASIATIC CORPORATION

MANIK CHOWK, P. O. 12, ALIGARH (INDIA).


## KIKO NI MIMO




**Olola Oloye Enahoro so wipe, ni akoko yi, ko si awon abobaku mo ninu awon onimoto ilu Ibadan ko si oniwakuwa mo gbogbo won lo ti ko ofin oju ona.**

Ninu awon enia to gba ehun nipa rirora wa moto ni Dokita Agbaje wa, Gbogbo awon Onikeke npo si owo osi, Oalmoto arin si owo osi. E ko ba ri i nigbati iku sare jiajia kuro loju ona, Ko si iku tabi jamba moto nilu Ibadan.

# Eebu Ila Ni eyiyi?

Lakoko kan nilu Eko, awọn gbajumọ meji mba ara wọn ja, nigbati ekini ma dahun, o wipe "yio ba iya rẹ". Tani ko mọ wipe ebu nla ni eyiyi jẹ larin awa Y o r u b a. Pẹlu-pẹlu ẹniti nwọn bu iya rẹ yi jẹ ẹniti gbogbo enia mbọwọ fun, itiju nla mu ẹnikeji tobẹ ti o fi wipe, ha! I-ya mi lo bu yẹn ẹnikini tun dahun pe, "yio ba b a b a rẹ pẹlu".

Inu bi ẹnikeji bi o ti kuro nibẹ, ile Lọya Ọmọtaku Thompson (Montacute) lo lọ o ni on fẹ ki o ba on pe lẹjọ, o doju ti on li arin o d e gbamgba, o bu iya on. Nigbati ẹni k i n i riwe ipẹjọ gba, on na lọ gba Lọya Ṣingle (Shyngle) akuru yẹ'jọ ọkuurin na.

Adajọ Penington lo dajọ na Ọmọtaku sọ fun adajọ wipe eebu nla ni yio ba iya rẹ" jẹ nilẹ Yoruba nitorina fun oju ti o da ti on larin mujumuwa ki adajọ ba on gba Ọgọrun pọun lọwọ rẹ ati wipe ẹniti on pe lẹjọ yi ni owo rẹpẹtẹ ni Banki eyi na lo si gbojule ki o to fi abuku kan on larin gbamgba.

Nigbati Ṣingulu d i d e o b e r e lọwọ Ogbufọ wipe ki o ṣe itumọ yio ba iya rẹ fun adajọ k'o gbọ. Ogbufọ tumọ rẹ bayi pe "I' will meet your mother" Adajọ sọ wipe Kinla kini njẹ bẹ Ṣingulu sọ pe ọrọ na jẹ eyiti ko ni itunmọ.

Adajọ bere pe What is it that will meet your mother? nṣe ni Ọmọntaku bẹrẹ si wa awawi, eyi mu ki adajọ binu o ni ki ẹniti o pe ẹjọ lọ san ọgọrun Pọun fun ẹniti nwọn pe lẹjọ ko lọ san pọun mẹwa si kotu. Gbogbo enia lo bẹrẹ si kan sara si adajọ na ati si Lọya Ṣingulu fun ọgbọn ori rẹ.

Nisisiyi awọn ẹlẹjọ mejeji nwọnyi mbẹ lode ọrun niwaju adajọ to ju adajọ lọ. Eyi fihan wa wipe kosi eebu ninu yio ba iya enia".

Ọrọ lasan ni.


## CASORINA

### Fun Awọn Ọmọ Ọwọ ati awọn Ọmọ Kekeke

Egbogi fun Aigbọnsẹ Ọmọde. Jẹdijẹdi ati oriṣiriṣi ni aisan ti ima mu inu rirun wa fun Ọmọde.



Aigbọnsẹ daada ni ima mu oriṣiriṣi aisan miran ti ima yọ Ọmọde lẹnu jade. Ailesun daada, jija wọnran-wọnran, ilọnu, jẹdijẹdi, Igbona-Ọmọde, ati ọpọlọpọ aisan bawọnyi ni aigbọnsẹ daada ma nmu wa sara Ọmọde. CASORINA ni egbogi atata ti o dara lati lo f u n Ọmọde fun awọn aisan wọnyi.

LILO RẸ:—Ṣibi kekeke kan lẹmẹta lojọ pẹlu omi to lọ wọwọ.

IGO KAN ṢILE MEJI - ABỌ (2s. 6d)

AWỌN TI NPIN FUN TITA NI:—

**THE ALBAN PHARMACY**

2, VICTORIA STREET, LAGOS NIGERIA.



## Let's have MUSIC! HEAR THE LATEST HIT NUMBERS

Read the list of popular titles

JZ 6037 Bo Ba Sorun / Iya Egbe) Victor Olaiya & His Cool Cats Orchestra.

" 6038—Emi O Se Ola / Konkoji) Victor Olaiya & His Cool Cats Orchestra.

" 6052—Kusimilaya I / Yanboss) " Victor Olaiya & His Cool Cats Orchestra

" 6053—Kilo Se E / Kusimilaya II) Victor Olaiya & His Cool Cats Orchestra.



JZ 6050—The Gentleman in the Wardrobe / The Lady with the Pancake Make up) Bobby Benson & His Havana Orchestra.

" 6051—Mamma Kiapo / Uncle Joe) Bobby Benson & His Havana Orchestra.

" 6048—Erin Folami / Oju Lo Pesi) Adisa Danbawa & His (Apala) Band.

" 6049—Egbe Mesho / Karimu Ajose) Adisa Danbawa & His (Apala) Band.

Sold by all the best stores




"HIS MASTER'S VOICE" Yellow Label RECORDS

Distributed by THE UNITED AFRICA COMPANY OF NIGERIA LIMITED


Printed & Published by The Union Printing and Publishing Company. 28, Kosoko Street P. Box O. 467 Lagos Phone 23570